

FOUNDATION FOR BLACK COMMUNITIES

# Ìtọ́sọ́nà Fún Olùfìfẹ́hàn

## Owó Ìrànwọ́ Fún Èrò Àtinúda Àwọn Aláwọ̀dúdú

2023

Funded in part by the Government of Canada's Black-Led Philanthropic Endowment Fund

Canada

# Nípa Ìpìlẹ̀ fún àwọn Àwùjọ Aláwọ̀dúdú

Àwọn àwùjọ aláwọ̀dúdú ti ń pè fún ọ̀nà tuntun sí iṣẹ inúre. The Foundation for Black Communities (FFBC) ni a gbé kalẹ̀ láti mu ìpè na ṣẹ àti láti ri dájú wípé gbogbo ènìyàn aláwọ̀dúdú àti àwùjọ wọn le ṣe rere kí wọ́n sì ní àjọ to fi ìtumọ̀ sí ọjọ́ ọ̀la wọn.

A gbe kalẹ̀ ní ọdún 2020 pẹ̀lú ìṣe láti mu àyípadà bá àwọn agbègbè, FFBC jẹ́ iṣẹ́ inúrere ti Canada ti a ya sọ́tọ̀ láti ri dájú wípé àwọn àjọ tí wọ́n ní aṣíwáju aláwọ̀dúdú, tí wọn sin àwọn aláwọ̀dúdu, ti àfojúsùn wọn sì jẹ lórí àwọn aláwọ̀dúdú, ní ohun àmúlò tí wọn nílò láti ní ipa tó ní ìtùmọ̀.

## Owó Ìrànwọ́ fún Èrò Àtinúda Àwọn Aláwọ̀dúdú: Afárá àti Ìkọ́ 2023

Owó Ìrànwọ́ fún èrò àtinúda àwọn aláwọ̀dúdu ti FFBC: Afárá àti Ìkọ́ 2023 jẹ́ ìdókòwò pàtàki bi $8.9 million láti fọwọ́sí àti láti ṣe àtìlẹyìn fun àwọn ìpìlẹ̀ṣẹ̀ tó ni ipò fun ọ̀nà àbáyọ, ti adarí wọn wa láti àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdu ní Canada, ti wọn sì òye to jọjú fun àwọn ètò owó ìranwọ́ ọjọ́ iwájú.

Owó Ìranwọ ti Afárá àti Ìkó ló ṣe ìpèsè ọlọdún kan to rorùn láti jẹ́ kí agbára àwọn àjọ tí wọ́n ní aṣíwáju aláwọ̀dúdú, tí wọn ń sin àwọn aláwọ̀dúdu, ti àfojúsùn wọn sì jẹ lórí àwọn aláwọ̀dúdú, àwọn àjo onínúre àti àjọ tí kò wà fún èrè jíjẹ, pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ́ pọ̀ si. Kí wọ́n sì dojúkọ ìwa ẹlẹ́yàmẹyà sí àwọn aláwọ̀dúdú, kí wọn mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ àti àbájáde ètò ọrọ̀ ajé ti àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú.

Ìfiféhàn ma ṣí sílẹ̀ láti ọjọ kejidínlógun oṣu kejìlá ọdún 2023, a si parí ní ọjọ́ kíni oṣù kejì ọdún 2024, ni aago méjìlá ku ìṣẹ́jú kan lọsan PT.

Funded in part by the Government of Canada's Black-Led Philanthropic Endowment Fund
Canada

# Ọ̀nà wa

FFBC jẹ̀ àgbékalẹ̀ àkọ́kọ́-irú-ẹ, ìlèpa wa sì ni láti ní òye, ìdámọ̀, kí a si àjọyọ ọ̀nà àbáyọ ni àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdu. Sùgbọ́n lákọkọ, a gbọ́do kọ́kọ́ wo inú àwọn àwujo láti ṣe ifilọ̀ fun àwọn owó ìranwọ́ àti àwọn èto ọjọ́-iwáju. A nílo ohun àti ìmòyè ti gbogbo àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú. Pàtàkì àwùjọ ní ìdí ti FFBC ṣe gba àwòṣe Ubuntu to kópa ninu ìmòye ṣiṣe owó ìrànwọ. Àwòṣe Ubuntu to kópa ninu ìmòye ṣiṣe owó ìrànwọ ni o dá lóri èrò wípé a wonu ara wa, àti pe a ipò wa lè ní ìlọsíwájú nígbà ti a bá ń ro ìlọsíwáju àwọn to wà nì àyíká wa.

Ọ̀nà yi ló fi àtẹnumọ́ to gbópọn sórí òye, ọgbọn àtinúda, ìrírí, àti èrò àtinúda ti àwọn tó súmọ́ jùlọ̀ nínú àbáyọ èsi èto yí. Gbogbo àwọn ìwé ififẹ́hàn ni àwọn ọmọ ẹgbẹ àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú ma ṣe àtúnyẹ̀wo ẹ. Àwòṣe Ubuntu to kópa ninu ìmòye ṣiṣe owó ìrànwọ ni ó fi ìgbẹ́kẹ̀lé, òfin, àti àjọ si àárín ìmòye rẹ̀, ti FFBC si ńlo ọ̀nà yí láti jẹ́ kí iṣẹ́ onínúure di tiwantiwa.

FFBC tún mọ̀ nípa ìtan àti iṣẹ pàtàkì tó ń ṣe àtìlẹyìn fún àwọn awùjọ tó ní ìdojúkọ lori ìdíwọ́ tó pọ̀ jùlọ ti wọn si ní ànfànní tó kéré jùlọ̀ si owó ìranwọ́ to rọ̀ mọ́ ìdájọ́ ojú ọjọ́, ìdájọ́ aìlera ,àti ìdájọ́ àpejúwe akọ àti abo. Èyi tí ṣe 2SLGBTQI+, obìrin àti ọmọbìrin, àwọn ọmọ ẹgbẹ àwujọ àwọn to ti ṣe àyípadà ìṣẹ̀dá wọn, àwọn tó ǹ gbe pẹ̀lu owo ọ̀yà kékeré, àwọn aláìlera, àwọn odi, àwọn aṣíkiri, àwọn tí wọn ti ṣẹ̀wọ̀n rí, àti awọn tí kò ní oúnjẹ tó dájú.

FFBC ti farajin láti ṣe àtìlẹyìn fún àwọn ìkoríta, tí kìí ninilára, ona to ní ìdájọ, to le jẹ afará tó sì lè kọ́ ọjọ́ ọ̀la tí gbogbo àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdu ti ma ṣe rere.

Owo Ìrànwọ́ ti Afára àti ìkọ́ ni a ti ṣe ìfilọ re nípaṣè àwùjọ. Sibẹ̀síbẹ̀, a ri wípé eyì ni ìlàna àṣetúṣe tí a sì fojúsọ́nà fun kíkọ́ owó ìrànwọ́ ọlọ́dún púpọ̀ ní ọjọ́ ọ̀la nípasẹ̀ àkọkọ́ ṣe yi.



Funded in part by the
Government of Canada's Black-Led
Philanthropic Endowment Fund
Canada

# Yiyẹ

## Àwọn àjọ tó yẹ

Àwọn àjọ tó yẹ nìkan ló lè fìfẹ́hàn fún owó ìrànwọ́ ti Afárá àti ìkọ́.
Láti yẹ, àjọ gbọ́gbọ̀:

- **Jẹ àjọ ti àwọn asíwájú rẹ jẹ aláwọ̀dúdú, ní àfojúsùn fun aláwọ̀dúdu, tó sì ń sin àwọn aláwọ̀dúdú (B3).** Èyí túnmọ̀ sí wípé èyí tó pọ̀jù nínú àwọn adarí ní gbogbo ìpele nínu àwọn àjọ wọ̀nyí gbọ́dọ̀ jẹ́ aláwọ̀dúdu. Àkọ́kọ́ ìlépa àjọ́ yi ni láti ṣe àtìlẹyìm tó ní ìtumọ̀ kí o si fàyègba ìlọ́wọ́si àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdu. Ipa tó pọ̀jù nínu ètò iṣẹ́-ṣiṣe won gbọ́dọ̀ yan sísin àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú láàyò.

  Ìpìlẹ̀ fún àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú gba ọ̀nà àwùjọ-ti a ta ji, àṣetúnṣe, àti kíkọ́ to ni ìfojúsùn láti fi ìtumọ̀ si àjọ to ni àwọn adarí aláwọ̀dúdú, ní ìfojúsùn fún àwọn aláwọ̀dúdú, ti wọ́n sì ń sin àwọn aláwọ̀dúdú. Olùfìfẹ́han ni a máa bèrè lọ́wọ ẹ pé kó ṣe àpejuwe bi àjọ wọn tabi àjọ ti wọ́n bẹ̀rẹ ṣe jẹ eyi t o ni àwọn adarí aláwọ̀dúdú, ní ìfojúsùn fún àwọn aláwọ̀dúdú, ti wọ́n sì ń sin àwọn aláwọ̀dúdú.

- **Jẹ àjo onínure tó ti forúkọsílẹ̀, ti ó ní àdàpọ ti kò nu èrè nínú,**[other qualified donee](àwọn olùgbaowó míran tó yẹ)**, tàbí aláìní àdàpọ̀ ti kò nu èrè nínú tàbí ẹgbẹ́ tó ń ṣiṣẹ́ fún àjọ tó ní alábáṣepọ̀ aládàpọ̀.**

  Àwọn ẹgbẹ́ aláìdàpọ̀ lè jẹ́ ti àwọn aláwọ̀dùdù aláfọwọ́sowọ́pọ̀, ẹg bẹ́ àwọn akẹ̀ẹ̀kọ́, ẹgbẹ́ tó jọra, àtí bẹbẹ lọ.

- **gbọ́dọ̀ wà ní Canada.**

Funded in part by the Government of Canada's Black-Led Philanthropic Endowment Fund

Canada

## Àwọn Ìpìlẹ̀ṣẹ̀ tó Yẹ

Nígbà tí ó bá ti ku di ẹ̀ kí ẹ parí àwọn ìlànà ìfiféhàn yín, ẹ ma ní àǹfàní láti fi ìpilẹ̀ṣẹ̀ tí ẹ̀ ń gbèro ẹ hàn wá. Àwọn ìpilẹṣẹ̀ to bá yẹ nìkan ló ma ní àǹfàní sí owo ìrànwó. Látí yẹ, ìpilẹ̀ṣẹ̀ gbọ́dọ̀:

- **Sọ̀rọ̀ lórí ókéré jù ìkan ninu àwọn agbègbè ìfojúsìn mẹ́tèta** ti owó Ìrànwọ́ Afárá àti Ìkọ́: Dídojúkọ àwọn ẹléyàmẹyà àwọn aláwọ̀dúdú, ìlọsíwájú àbájáde àwùjọ, Ìlọsíwájú àbájáde ọrọ̀ ajé.
- **Sọ̀rò lóri ìkan tàbí jubẹ́lọ̀ nínú àwọn** Sustainable Development Goals **and** Social Determinants of Health**.** (nínú àwọn ìlépa Ìdàgbàsókè tó ṣe tójú àti ìpinnu àwùjọ lórí ìlera).
- **Se é múlò láàrín àsìkò tí à ń gbèro ẹ àti pẹ̀lú owó ìrànwọ́ tó wà.** Àrídájú wípé a ná owó ìrànwọ́ kí ó tó di Ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n, ọṣu kẹ́ta, ọdun 2025.
- **Má jẹ́ kí iṣẹ́-ṣiṣe tí kò yẹ tí a sàlàyé nísàlẹ̀ yi wà níbẹ̀.**

- **Àjọ Tí Kò Ní Òòlù Òfin Tí Kò Wà Fún Èrè Jíjẹ, Alafọwọsowọpọ̀ Àti Ẹgbẹ**

  Àjọ tí kò ní òòlù òfin tí kò wà fún èrè jíjẹ. àwọn alàfọwọ́sowọ́pọ̀ àtí ẹgbẹ́ gbọ́dọ̀ ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn àjọ tó ní òòlù òfin ti kò wà fún èrè jíjẹ àti àjọ onínure láti ní àǹfàní sí owo ìrànwọ ti FFBC. Ti àjọ yín kò bá ní alábáṣepọ̀ tó ní òòlù òfin ni àsìkò ìgbà tí wọ́n ń kọ̀wé ìfiféhan, àǹfàní wà láti fiféhàn.

  Ẹ Kíyèsi wípé FFBC máa bèrè fún ìwé àdéhùn tó ní ìfọwọ́sowọ́pọ̀ láarin àjọ tí kò ní òòlù òfin tí kò wà fún èrè jíjẹ tàbí ẹgbẹ́ àti àjọ alábáṣepọ̀ tó ní òòlù òfin, tó ní àlàyé lẹkunrẹ́rẹ́ àti ìdí ìfọwọ́sowọ́pọ̀.

Láti gba owó ìrànwọ́, gbogbo àjọ tí kò ní òòlù òfin tí kò wà fún èrè jíjẹ, oní ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ẹgbẹ́ máa nílo alábáṣepọ̀ tó ni òòlù òfin tí kò wà fún èrè jíjẹ tó bá di Ojọ́ kíni, **Oṣù Kejì, Ọdún 2024.** Ti ẹ bá ni ìbéèrè si nípa yíyẹ yín, ẹjọ̀wọ̀ ẹ kàn sí fund@forblackcommunities.org.

Funded in part by the
Government of Canada's Black-Led
Philanthropic Endowment Fund
Canada

## Àwọn Àjọ tí Kò Yẹ

Wọ̀nyí ni àwọn àjọ tí kò yẹ fún owo ìrànwọ́:

- Àwọn àjọ tí ko ni àwọn àdarí tó je aláwọ̀dúdu, ti kò ní ìfojúsùn fún àwọn aláwọ̀dúdú, àti àjọ ti kò sin àwọn aláwọ̀dúdú.
- Àjọ tàbí àjọṣepọ̀ tó wà fún èrè jíjẹ.
- Enìkọ̀ọ̀kan
- Ìgbékalẹ̀ ìṣòwo, ẹgbẹ́ oníṣòwò, àwọn ìyẹ̀wù tabi kondominiumu ti ìṣòwò.
- Àwọn àjọ ìsọ̀rí tabi agbègbe, bí ilé-ìwòsan, ilé-ẹ̀kọ, ilé-ẹ̀kọ́ aládáni, ilé ẹ̀kọ́ gíga, àwọn aláṣẹ ìlera, aláṣẹ ìlera ti ìjọba, ìgbékalẹ̀ ẹ̀kọ́, àti ìgbékalẹ̀ ìlera/àwùjọ́.
- Agbègbè tabi àjọ tó ni ìṣàkósò àjọ, bi ìjọba agbègbe, ìjọba ìgberíko, ati;
- Àwọn tí wọn lọ́wọ́sí iṣẹ́-ṣiṣe ọ̀ṣèlu, tí wón ń ṣe àtìlẹ́yin tàbí ìtakò fun ẹgbẹ́ ọ̀ṣèlú kankan, àwọn aṣojú ti a dìbòyan, tàbí olùdíje fún iṣẹ́ ìlú.



Funded in part by the
Government of Canada's Black-Led
Philanthropic Endowment Fund
Canada

## Àwọn Iṣẹ́-Ṣíṣe tí Kò Yẹ

Àwọn wọ̀nyí ni iṣẹ́-ṣíṣe tí kò yẹ fún owó ìrànwọ́ FFBC:

- Ìṣúwọ́ná tí kò pé;
- Rírà tàbí títa ọtí líle tàbí tábà líle, Ṣíṣe ìṣúwọ́ná fún ìwé aṣẹ tàbí ìwé ìyọ̀nda to jọra, olú owó fun àtúnṣe ibi tí wọn ti ń ta ọtí líle tàbí tábà líle;
- Iṣẹ́-ṣíṣe tó ń ṣe àtìlẹyìn tàbí àtakò fún ẹgbẹ́ òṣèlú, aṣojú tí a dìbòyàn, tàbí  olùdíje fún iṣẹ́ ìlú;
- Àwọn iṣẹ́-ṣíṣe ti ẹ̀sìn tàbi èyi tó níse pẹ̀lú kíkópa ninu ipele ìgbàgbọ́ kankan (bi àpẹrẹ; ìjọ̀ tó ní ile ìta oúnjẹ le ní agbègbè le kọ̀wé ìfìfẹ́han fun ìpèsè àti owo àwọn òṣìṣẹ́, sùgbọ́n kò gbọdọ̀ jẹ ti ẹ̀sìn);
- Olú owó fun àtúnṣe àtí àtúntò ibi ìjọsìn;
- Bíbẹ̀ fún owó ìrànwo tàbí ìpolongo fún owó;
- Iṣẹ́-ṣíṣe, ètò, tàbi, iṣẹ́ tí kò ṣe àǹfàní fún àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú ni Canada;
- Iṣẹ́-ṣíṣe, ètò, tàbi, iṣẹ́ tí a gbé jáde ni ibòmíràn yàtọ̀ sí Canada, àti;
- Iṣẹ́-ṣiṣe tí a ti parí, owó ti a kojọ, kí ó tó dí àkókò ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ àkànṣe tí owó ìrànwọ́ FFBC pese.



Funded in part by the
Government of Canada's Black-Led
Philanthropic Endowment Fund
Canada

# Ìṣèwadi Àwùjọ Àwọn Aláwọ̀dúdú

## Àwọn Ipele fún owó ìranwọ́

Owo ìrànwọ́ Afárá àti Ìkọ́ ma gba ìwé ìfiféhan láti ọwọ́ àwọn àjọ B3 to yẹ ni ipele ọ̀tọ̀tọ ti wọn bá ti ń ṣiṣẹ́ lóri iṣẹ́ àkànṣe tàbi ètò tó ní ìpa rere lórí àwùjọ aláwọ̀dúdú. Ipele owó ìrànwọ́ mẹ́ta ló wa. Ẹ mu ipele owó ìrànwọ́ to ba ta òjìjí sí àìní àjo tàbí ẹgbẹ yin. Àwọn Ipele owo ìrànwọ́ mẹta na ni:

**Gbòógì :** Fún owó ìrànwọ́ tó tó $40,000 fún àwọn iṣẹ pàtàki tí kò nì ṣe pẹ̀lú ètò ṣíṣe;

**Ayárabíàṣá:** Fún owó ìrànwọ́ láti $40,000 si $100,000 fún ìdókòwò sí àwọn èrò àtinúda tuntun tàbí fún ìmúgbòro àwọn ètò tàbí iṣẹ́ tó ti wà tẹ́lẹ̀;

**·Olú owó fun àwọn agbègbè:** Fún owó ìrànwọ́ tó tó $250,000 fún ìdókòwò sí olú iṣẹ́ àkànṣe àbí iṣẹ́ amáyédẹrùn fún àwùjọ.

Funded in part by the
Government of Canada's Black-Led
Philanthropic Endowment Fund

## Gbòógì| fún owó tó tó $40,000

*Fún àwọn iṣẹ pàtàki tí kò nì ṣe pẹ̀lú ètò ṣíṣe*

Àwọn àjọ tàbí ẹgbẹ́ tó yẹ le kọ̀wé ìfìfẹ́hàn fún owó tó tó $40,000 lati ṣe àwọn ìnkan tó ṣe pàtàkì tó sì bá àìní owó ìrànwọ́ pàdé. Ìpèlè yi ma ṣètò owó ìrànwọ́ fun àwọn iṣẹ́-ṣíṣe tó ṣe pàtàki tó sì rọ̀ mọ́ àṣeyọrí ìṣẹ́ àjọ tàbi ẹgbẹ́. Olùfìfẹ́hàn lé fi ìwé àkọsí ìgbèrò wọn fun òṣìṣẹ́, àwọn tí kìí ṣe òṣìṣẹ́, àti owó ìṣàkóso, sílẹ̀ tí kò tan mọ́ ṣíṣètò'

**Àwọn Àpẹrẹ**

- Àjọ B3 bèrè fún owó ìrànwọ́ láti fi gba òṣìṣẹ́ tí yọ̀ gbé àwọn iṣẹ́ ètò tóń sàtìlẹyìn fún àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdu jáde.
- Ẹgbẹ́ àwọn ọ̀dọ́ aláwọ̀dúdú fífẹ́hàn fún owó ìrànwọ́ láti gba olùdámọ̀ràn fún ìdàgbàsókè ìgbékalẹ̀ ètò ìṣèjọba.
- Àjọ onínúre bèrè fún owó ìrànwọ́ láti ra àwọn àga tuntun fún ilé iṣẹ.
- Àjọ B3 ra àwọn ohun ẹrọ amúṣẹ́ya.

Funded in part by the Government of Canada's Black-Led Philanthropic Endowment Fund | Canada

## Ipele Ayárabíàṣá| $40,000 si $100,000



*Ìdókòwò sí àwọn èrò àtinúda tuntun tàbí fún ìmúgbòro àwọn ètò tàbí iṣẹ́ tó ti wà tẹ́lẹ̀.*

Àwọn àjọ tàbí ẹgbẹ́ tó bá yẹ le kọ̀wé ìfiféhàn fún owó láti $40,000 sí $100,000 fún ìṣé tuntun tàbí ètò tó ti wà tẹ́lẹ̀, làti mu ìlọsíwájú bá àwùjọ àti ètò ọrọ̀ ajé ní agbègbè àwọn aláwọ̀dúdú, tí ó fi mọ́ ìwádi, ìgbékalẹ̀, ìṣẹ̀ṣẹ̀bẹ̀rẹ̀, àgbéyẹ̀wò àwọn ìpilẹ̀ṣẹ̀.

- **Èrò àtinúda tuntun àti ọna àgbéjáde:** Àwọn àjọ tàbí ẹgbẹ́ tó ń kọ́ tàbí tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ fẹ́ bẹ̀rẹ̀ ètò tàbí isẹ́ ìsìn tuntun, dídán ọ̀nà ágbéjáde tuntun wọ̀, ṣísèwadi tàbí ṣiṣedanwo le kọ̀wé ìfiféhàn fún owó láti $40,000 si $75,000.

- **Ìmúgbòrò àwọn ètò tàbi iṣẹ́ ìsìn:** Àwọn àjọ tàbí ẹgbẹ tó bá lérò láti dàgbà tàbi tójú àwọn ètò tàbí iṣẹ ìsìn tó wa tẹ́lẹ̀ le kọ̀wé ìfiféhàn fún owo láti $40,000 sí $100,000. Àwọn àjọ gbọ́dọ̀ ṣàlàye àwọn ètò tàbi iṣẹ́ ìsìn to ti wà tẹ́lẹ̀ sínú ìwẹ́ ìfiféhàn wọn.

**Àwọn Àpẹrẹ̀**

- Ilé iṣẹ́ onínúre kan ń gbèrò láti ra ẹ̀rọ amóunjẹ tutù fun ilé oúnjẹ tuntun kan.
- Àjọ tí kò wà fún èrè jíjẹ tó ń  ṣiṣẹ́ lórí oríṣiríṣi ètò tàbí iṣẹ, fẹ gbé amóhùn-máwòrán tó yarantí jáde, gẹgẹ́ bîinkan làra ọ̀na ìbáraẹnisọ̀rọ̀ wọn.
- Ilé ìfoúnjẹ pamọ́sí to fẹ́ ṣe àfikún sí ohun èlò wọn tí wọ́n sì nílò láti ra ọkọ láti bá àiní àwọn olùbára tí wọn ti dàgbà pàdé.
- Ilé àbò to ra aṣọ òtútù fún àwọn ọdọ ni ilé ìyípadà wọn.
- Àjọ B3 tó ti ṣe ìwádìí fún ibi-ìṣeré ìdárayá tuntun fún àwọn ọ̀dọ́ ní agbègbè wọn.
- Àjọ B3 tó ń sin àwùjọ gbèrò láti ṣàkóso ìwádìí àpéjọ ọ̀mọ̀wé tó ma ní ipa lórí àwọn òṣìṣẹ́ aṣíkiri aláwọ̀dúdú.
- Àjọ B3 ti àwùjọ ṣàkóso àgbéyẹ̀wò tó nípọn fun ètò tó ti wà tẹ́lẹ̀.
- Ẹgbẹ́ àwọn òbí aláwọ̀dúdú máa fẹ́ràn láti sewadi ìdásílẹ̀ àjọ tí kò wà fún èrè jíjẹ láti fí ṣe àtìlẹyin fun ìdánilójú oúnjẹ fun àwọn agba aláwọ̀dúdu ninú àwùjọ.

Funded in part by the
Government of Canada's Black-Led
Philanthropic Endowment Fund
Canada

## Olú owó fún àwọn agbègbè | fun owó tó tó $250,000



*Ìdókòwò sí olú iṣẹ́ àkànṣe àbí iṣẹ́ amáyédẹrùn fún àwùjọ.*

Àwọn àjọ tàbí ẹgbẹ tó bá ní èrò àtinúdá tó tóbi tósì dáwọnlóju tí èrò wọn si le mú ìtẹ̀síwájú ba àwùjọ àti èto amáyédẹrùn ọrọ ajé fún àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdú. Àwọn àjọ yi le kọ̀wé ìfiféhàn fún owó tó tó $250,000 lati fi ru ètò, iṣẹ́ ìsìn sókè. Èrò tí a ní fún owó ìranwọ́ ni láti fi dókoòwò sí àwọn àjọ tó ṣe pàtàkì sí ẹ̀kà tàbí agbègbè wọn, ti won ṣe ojúṣe wọn sí àwùjọ àwọn aláwọ̀dúdu, tí wọ́n sì ń fi ìdì àyípadà rere múlẹ̀.

Owó ìrànwọ́ wà fún ìmáyédurùn àjọ, àgbègbè tabì bibá àìní àwọn aláwọ̀dúdú pàdé ní ti orílẹ̀ èdè tàbi ìgbèríko (Òkéré tan ẹ̀kun méjì). Àwọn àjọ gbọ́dọ̀ tí ṣe ìfimúlẹ̀ èrò àtinúdá wọn nípasẹ ìwadi, àwọn àìní, tàbí àwọn ọ̀nà to jọ́ra sí èyí láti fi mọ̀ wípé ònà ìgbéjáde wọn ma ṣiṣ+ẹ́. Ó lè jé èyí tí a ti ru sókè tàbi èyi tí o ṣeéṣe láti rọ́pò.

**Olùfiféhàn gbọ́dọ̀ fí ìwé owó ọdún méji sílẹ̀, àwọn ìwé ètò ìṣúwóná ọdọdún àti àwọn iwé tó je àpèjúwe iṣẹ́ won títí di àkokò yí.**

### Àwọn Àpẹrẹ

- Àjọ B3 tó bá ń bèrè fún owó ìrànwọ́ fún ìtẹ̀síwáju láti fi da ilé itọ́jú fùn àwọn àgbàlagbà aláwọ̀dúdu sílẹ̀.
- Àjọ ti àwujọ̀ tó bá ń bèrè fún owó ìrànwọ́ fún ìkọ́lé tí àwọn ènìyan lè sanwọ́ ẹ̀.
- Ẹgbẹ́ àjọ àwọn obìrin tí wọn nílo owó ìranwọ láti fi tún ilé ti yo ma ṣe itọ́jú àwọn ti wọn bọ́ nínu ewu ènìyan gbígbe káàkìri.
- Ẹgbẹ àwọn àgbẹ̀ tàbi àwọn agbé ìnkan jáde aláwọ̀dúdu tó ń gbèrò láti ra àwọn ohun èlò àlájọlò ni àwujọ̀ fún ìtẹ̀síwájú ọ̀rọ̀ oúnjẹ, ìpèsè óuńjẹ, àti ilé ìta oúnjẹ.
- Àjọ tí kò wà fú èrè jíjẹ tó wà ní ìgbèríko tabi èka àríwa tó fẹ́ ilé ìtajà àjọlò fún àwọn òǹtajà, oníṣòwò kékèké, àti àwọn onișẹ́ àdáni aláwọ̀dúdu.

Funded in part by the
Government of Canada's Black-Led
Philanthropic Endowment Fund
Canada

# Ìlànà Yíyàn

Gbogbo Olùfìfẹ́ han láti àwọn àjọ tó yẹ ni àwọn ọmọ ẹgbẹ́ àwùjọ aláwọ̀ dúdu ma ṣe àtúnyẹ̀wò ìwé ti wọn si ma yan nínu wọn. Àjọ tó yẹ ni àwọn àjọ tó ni àwọn adarí aláwọ̀dudu, àfojúsùn fún aláwọ̀dúdu, àti ti wọ́n sì ń sin àwọn aláwọ̀dúdú, àwọn àjọ onínúre tí wọn sin aláwọ̀dúdú, àjọ tí kò wà fún èrè jíjẹ, àti àwọn tó wà ní Canada. Gbogbo olùfìfẹ́han ni ó ma gba ìtanijí abájáde ìwé ìfìfẹ́hàn wọn ni oṣù kẹ́ta ọdún 2024.

**Àwùjọ àwọn tóń yan Olùfìfẹ́han**

Awọn àwùjọ tó ń yan olùfìfẹ́han ni wọ́n ma yan àwọn ìwé ìfìfẹ́han tó kún oju òṣùwọn, èyí to ma jẹ bí ìdúró lọ́dọ̀ àwọn ìgbìmọ ìgbówósílẹ̀ FFBC. Àwọn àwùjọ yi ni ó ma jẹ ìdajì nínú àwọn olùfìfẹ́han àti ìdaijì nínu àwọn ọmọ ẹgbẹ agbègbe. Olùfìfẹ́hàn ma ní àǹfàní láti ṣe ìdámọ lǎsìkò ìfìfẹ́hàn tí wọ́n bá fẹ́ darapọ̀ mọ́ àwùjọ àwọn tóń yan olùfìfẹ́hàn. Ọna ìkopá ló ní ìfojúsùn láti dí ààyè tó wà laarin àwọn agbègbè, san owo àwọn ètò àti àwọn olórí tóń ṣiṣẹ́ pèlu àwọn agbègbè tí a dámọ̀, láti fi okun fún ìgbẹ́kẹ̀lé, àti atìlẹ́yìn fún àwọn awùjọ tó ní ìfojúsùn àti èrò àyípadà rere fún agbègbè àwọn aláwọ̀dúdú.

### Awọn Ohun Àmúyẹ fún Yíyan

Ìpinu ni a máa ṣe látàri bí ìpilẹ̀ṣẹ̀ ti à ń gbèro fún àwọn àjọ B3 to ba yẹ bá a ṣe si:
Tí ó bá bá àwọn ohun àmúyẹ fún yíyan ipilẹ̀ṣẹ̀ mu bíi
- Sọ̀rọ̀ nípa ókéré tan ìkan nínu àwọn ibi àfojúsùn mẹta tí a gbé kalẹ̀
- Sọ̀rọ̀ lóri ìkan tàbí jubẹ́lọ̀ nínú àwọn Sustainable Development HYPERLINK "https://sdgs.un.org/goals"Goals and Social Determinants of Health.
- Se é múlọ̀ láàrín àsìkò tí à ń gbèro ẹ pẹ̀lú owó ìrànwọ́ tó wà.
- Kí àwọn iṣẹ́ ṣíṣe tí kò yẹ máṣe wà nínu ẹ̀.
- Ní abájáde rere fún agbègbè àwọn aláwọ̀dúdú ti Canada.



Funded in part by the Government of Canada's Black-Led Philanthropic Endowment Fund

# Àwọn Ohun tó ṣe Pàtàkì fún Ìjábọ̀

Àwọn àjọ tí a búwọ̀ lù fún owo ìrànwọ́ gbọ́dọ̀ tọwọ́bọ̀we àdéhùn owó ìrànwọ́ kí wọ́n tó gba owó ìrànwó wọn. Fún ti ìwé àdéhùn lórí owó ìrànwọ́, àwọn akópa gbọ́dọ̀ kópa níni ipele ìjábọ̀ méji. Ìlépa wa ni láti jẹ kí a lè kẹkọ láti ọ̀dọ̀ àwọn tíó fẹ́ gbowó ìrànwọ, alábàṣepọ̀ pẹ̀lú Afárá àti Ìkọ́, ṣe àtìlẹyìn fún àwọn àwùjọ àti àlàyé ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ nípa ọ̀na ìgbówósílẹ̀ wa.

1 ·**Àyẹ̀wò ìgbà-àárín rámpẹ:** Tó bá di ìgbà-àárín sí ìpìlẹ̀ṣẹ̀ olùgba, àwọn òṣìṣẹ́ FFBC máa kàn sí òlùgbà láti sọ̀rọ̀ lóri àwọn ìmúdójúìwọ̀n to ga, ìdojúkọ àti àṣeyọrí tí wọ́n ti dojúkọ. Àwọn ìpàdé yi máa wáye lóri amóhùn máwòràn ayélujára ti elérò púpọ̀ tàbi ẹ̀rọ alágbéká.

2 **Èsì Ìkẹyìn:** Tí iṣẹ́-àkànṣe bá ti parí ìṣẹ-ṣìṣe tí ó gba owó ìrànwọ́ fún, tí kò gbọdọ́ kọjá ọjọ́ kokànlélọgbọ̀n, oṣu kẹ́ta, 2025, a máa ní kí àwọn olùgbà parí èsì ìkẹyìn lórí ìpilẹ̀sẹ̀ wọn àti èsì rẹ.

**Àwọn àlàyé tí a kójọ nínú ìwé èsì yí ni a lè pín pẹ̀lú ìjọba Canada tàbí kí a lò ó nínú iṣẹ́ ìpìlẹ̀ fún Àwùjọ Àwọn Aláwọ̀dúdú. Ẹ kíyèsi wípé FFBC kò ní pín àwọn ọ̀rọ̀ yín tó jẹ ti ara ẹni pẹ̀lú ìjọba Canada.**

Funded in part by the Government of Canada's Black-Led Philanthropic Endowment Fund | Canada

# Bí a Ṣe lè Fìfẹ́hàn

Bi ẹ bá ti ṣetàn láti fìfẹ́hàn, ẹ fi ìwé ìfìfẹ́hàn yín sílẹ̀ lórí àbáwolé ayélujára wa. Ìwé ìfìfẹ́hàn yí ní ó ma wà fún lílò ní oríṣiríṣi ọ̀nà kíkà lórí ìtàkùn ayélujára wa, a sì gbà yín níyànjú wípé kí ẹ ṣe àkọsílẹ̀ àwọn èsì yín àti pé kí ẹ gba gbogbo ìwé àfikún tí ẹ nílò, kí ẹ tó bẹ̀rẹ̀ síni fi èsì yín sílẹ̀ sórí abáwọlé ayélujára wa. Ẹ lè ṣe ìtọ́jú àti àtúnyẹ̀wò àwọn èsì ìfìfẹ́hàn yín kí ẹ tó fi sílẹ̀ pátápátá.

DNígbà tí ẹ bá ńṣe ìfìfẹ́hàn, a máa ní kí ẹ ṣe àtúnyẹ̀wò àti ìfọwọ́sí àwọn àdéhùn owó ìrànwọ́ tówà lórí ayélujára. Bí ẹ bá ti ṣe àtúnyẹ̀wò àdéhùn yí nínú ìfìfẹ́hàn yín, àwọn òfin àti ipò owó ìrànwọ wa hàn tàárà sí i yin, a sì lè jẹ́kí ìdẹ̀rọ̀ dé bá ètò ìsanwó ní kíákíá àti lásìkò fun àwọn olùfìfẹ́hàn to bá yege. Ìfìfẹ́hàn yí ní a ma kọ ní èdè gẹ̀ẹ́sì àti Faranse.

Àyè dí ẹ̀ ní a ma fi sílẹ̀ fún àwọn olùfìfẹ́hàn tó ba fẹ́ fífẹ́hàn nípa ti ọ̀rọ̀ ẹnu. Ti eleyi bá jẹ oun tí ẹ fẹ́, ẹ gbọ́dọ̀ bẹ̀rẹ̀ àyè fún ìpàdé nípa lílo ọ̀rọ̀ àsopọ̀ yi **link**, bíbẹ̀kọ́ a ò ní yẹ ìwé ìfìfẹ́hàn yí wọ. Àyè wà láti ọjọ́ kẹjọ, oșù kínní sí ọjọ́ kokàndínlógún oșù kínní, ọdún 2024.

Ti fún ìdí míran, e o le fí ìwé ìfìfẹ́hàn yín sílẹ̀ lórí àbáwọlé ayélujára wa, ẹ jọ̀wọ́ ẹ kàn sí àwọn òṣìṣẹ́ FFBC ní fund@forblackcommunities.org kí ótó dí àsìkò tí ìfìfẹ́hàn ma dópin. A ma ṣe àtìlẹ́yìn fún yín ní ìwọ̀nba ti agbára bá ka.

**Ìfìfẹ́hàn ma ṣí sílẹ̀ ní ọjọ kejìdínlógún, oṣù kejílá, ọdún 2023, ẹ sì gbọ́dọ̀ mú sílẹ̀ ó pẹ́ jù ní ọjọ́ kínní, oṣù keji, ọdún 2024 kí aago méjìlá òsán kú ìṣẹ́jú kan to lù (11:59PM PT).**

**BỌTÌNÌ ÀBÁWỌLÉ SÓRÍ ÀYÉLUJÁRA**

# Àsìkò

**Asiko Ibere Ififehan**
Ojo kejidinlogun, osu keji, odun, 2023

**Asiko Igba iwe Ififehan pari**
Ojo kini, osu keji, Odun 2024, ni aago mejila ku iseju kan  (11:59 PM PT)

**Ayewo Iwe Ififehan**
Osu keji, odun 2024

**Itaniji fun awon olufifehan**
Osu keta, Odun 2024

**Asiko Igbe owo sile**
Ojo kokanlelogbon, Osu keta, Odun 2024



Funded in part by the Government of Canada's Black-Led Philanthropic Endowment Fund | Canada

## Ọ̀rọ̀ lórí Àwọn Tí ẹ Lè Básọ̀rọ̀

Bí ẹ bá ní ìbéèrè síwájú si, ẹ jọ̀ọ́, ẹ kàn sí wa ní fund@forblackcommunities.org tàbí kí ẹ lo ọ̀rọ̀ àsopọ̀ yí link láti gba àyè fún ìpàdé.

Tí ẹ bá fẹ́ bawa sọ̀rọ̀ lórí ẹ̀rọ alágbéka, ẹ pe 1.833.44BLACK (442-5225)

## Ìfọwọ́sí

Owó ìrànwọ́ ti Afárá àti Ìkọ́ ní o ni àtìlẹyìn láti ọ̀dọ̀ Ìjọba Ìpílẹ̀ Canada àti Fondation Lucie & Andre Chagnon.

Funded in part by the Government of Canada's Black-Led Philanthropic Endowment Fund | Canada